OWE
Bi a ba ran'ni ni iṣẹ ẹru, afi t'ọmọ jẹẹ

# Irohin Yoruba

VOL X No. 469 MONDAY JULY 5, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe Iro'hin Yoruba

# OBA ADELE KEJI SE ASE APEJE F'OBA ALAKE

**EKO -- Enu ko irohin ni ase apeje ti Alaiyeluwa Adele Keji Oba Eko se ni Afin re (Iga Idunganran), ni ojo Abameta ti ise ojo kerindinlogbon osu ti o koja yi fun Oba Alake Abeokuta, Alaiyeluwa Ademola Keji lati ba a yo ayo Oye nla "K. B. E." ti Alaiyeluwa Elizabeth Keji Obabirin ilu Oyinbo fi da a lola, nigbati Obabirin Oyinbo na nse ajoyo ojobi ti odunni.**

Ẹsẹ awọn Ọba ati ti awọn Ijoye ati awọn enia pataki pataki ti Abẹokuta ati Eko ni o pe sibẹ, oniṣiriṣi fere ati ilu ni o ndun bi igbati nwọn nṣe ọdun Ileya.

Ọba Adele Keji sọ ọpọlọpọ ọrọ iwuri nipa iwa ati iṣe Ọba Alaiyeluwa Ademọla Keji Alake Abẹokuta bi o ti ṣe lo ọpọlọpọ igba ewe rẹ l'Eko ti o si ṣe ọpọlọpọ ire sibẹ laseko na. Ni ipari ọrọ rẹ, o sọ pe en ba Ọba na yọ pupọ fun oye nla na ti Ọba Ilu Oyinbo fi da a lọla, o si gba adura fun un.

Ninu awọn ti o sọrọ lọjọ na ni Ọlọla Dọkita Koworọla Abayọmi, Oloye Dọkita Akinọla Maja Baba Eko, ati Oloye Eletu Odibo ẹniti o dupẹ pupọ lọwọ Ọba Ademọla Keji nitori pe o wa jẹ ipe apejẹ Ọba awọn.

Ọba Alake sọ pe Ọba Adele Keji ni ẹniti o kọkọ fi ayọ rẹ han on lọna bayi ni ilu Eko ati larin awọn Ọba yoku, o si dupẹ lọwọ rẹ pupọ, o fi han pe o ju adọta ọdun lọ ti on fi gbe ilu Eko, o si sọ itan ilu na pẹlu itan igba aiye baba Ọba Adele Keji. Ninu ipari ọrọ rẹ lọjọ na o fun awọn Ijoye Ọba Eko ni imoran pe ki nwọn wa ni irẹpọ larin ara wọn ati pẹlu Ọba wọn lati le ma a fi ifẹ ati isowọpọ ṣe iṣẹ rere fun igbega ilu Eko.

Diẹ ti aye fun lati darukọ ninu awọn Ọba ati awọn Ọlọla ti o wa si ibi ase apejẹ na ni awọn Alaiyeluwa Ọba Akarigbo Iṣagamu, Ọṣilẹ Oke-Ọna, Abẹokuta, Agura Gbagura, Abẹokuta, Olubara Ibara, Abẹokuta, Dọkita Maja ati Iyawo rẹ, Ọlọla Mohamadu Ribaju, Dọkita J. A. Doherty, Ọgbẹni S. O. Shonibarẹ, Onidajọ - Kekere H. O. Lucas, Onidajọ - Agba Adetokunbọ Ademọla, Alufa T. A. Dedẹkẹ, Ọlọla Alhaji S. O. Gbadamosi, Alhaji M. A. Okunnu, Arẹmọ Ọba Eko, Sanni Adele, Alfa S.L. Ayẹni ati ọpọlọpọ awọn Ọlọla bẹẹbẹẹ ti ko si aye lati darukọ wọn.

Ade a pẹ lori, bata a pẹ l'ẹsẹ awọn Ọba, Kabiyesi!



Aworan awọn Ọba nibi ase aseyẹ ti Ọba Adele Keji ṣe fun Ọba Alake Abẹokuta ni Iga-Idunganran.

## NWON SI ERE FATHER COQUARD

ABẸOKUTA -- Ni aipẹ yi ni awọn Ijọ Sọọṣi Aguda Abẹokuta ati gbogbo Ẹgba ṣe Isin ajọyọ ni Iranti Ẹni-Ọwọ Alufa Father J. M. Coquard ẹniti o ti jalaisi ni ọdun kẹdọgbọn sẹhin.

Ọba Alaiyeluwa, Ademọla Keji K.B.E., C.M.G. Alake Abẹokuta ni o ṣi ere - aworan Ologbe Ẹni-Ọwọ Father Coquard na ti a fi idẹ ṣe. Ẹniti o ṣe Alakoso Isin iranti pataki na ni Ẹni-Ọwọ Julọ Archbishop L. H. Taylor o si sọ ọrọ iwuri pupọ nipa iṣe ati iwa Ologbe na.

Ẹni-ọwọ Alufa Father J. M. Coquard jẹ Alufa-Oniṣegun Oyinbo ti o kọkọ bẹrẹ iṣẹ itọju alaisan ni ile egbogi Sacred Heart Hospital ti iṣe Ile Iwosan Awọn Ijọ Aguda. Fun odidi ogoji ọdun ni Alufa yi fi ṣe iṣe iwosan fun ẹnikẹni ti o ba wa sibẹ ki o to ku.

Titi di oni ni awọn Alagba ni Abẹokuta ati

Wo oju ewe kẹrin



Father Bariff Ẹni-ọwọ julọ Archbishop Taylor Ọba Olowu Oloye V. B. Adebiyi ati Ọba Alake.

## Egbe Ilu Eko Ko Faramo Imoran Mbadiwe

EKO- Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o kọja yi ni "Ẹgbẹ Ilu Eko pe ipade gbogbo-gboo kan si gbangba Isalẹgangan, lori eto itunluṣe pẹlu ọpọlọpọ ile wiwo-lulẹ ti Ijọba ngbero lati ṣe lọwọ-lọwọ yi.

Awọn enia pataki pataki ti o wa si ipade na ko lonka nwọn pọju, gbogbo ohun ti nwọn si da ni imoran ni gbogbo awọn ti o pe sibẹ fi ara mọ Oloye Amodu Kosoko ni alaga ipade na, o si ṣe alaye l'ẹkun lori ohun ti nwọn ṣe ipade na.

Ọgbẹni S. L. Ayẹni sọ pe on ṣakiyesi pe laipẹhinwa ti nwọn ti gbe eto itunluṣe pẹlu ile-wiwo lulẹ yi wa ni awọn ara ilu ko ti fi ara mọ ọ, ati pe Ọgbẹni Mbadiwe ko ka Ọba Eko ati awọn ijoye rẹ si ti wọn jẹ pe awọn ni pataki ninu Igbimọ Munisipa Eko, aika wọn si na ni o mu u yan awọn Ọgbẹni Kọla Balogun, H. O. Davies ati Essua ti awọn ara ilu ko ni igbẹkẹle si, sinu Igbimọ eto itunluṣe pẹlu ile-wiwo na.

Awọn Ọgbẹni Sadiki Sarumi, H. A. B. Fasinro, Muri Animashaun, Ọmọọba Adeleke Adedoyin ati Omidan Ibun Shepherd sọ ọrọ atako lori eto itunluṣe pẹlu ọpọlọpọ ile wiwo-lulẹ na, nwọn si ṣe alaye bi eto na ko ti ṣe dara rara fun ilu Eko.

Nwọn si mu ipade na wa si ipari pẹlu ipinnu pe, ki nwọn ti iwe ṣọwọ si Adele Gomina si awọn Igbimọ Iriju Ijọba Nigeria pe ki nwọn fi agbara eto itunluṣe pẹlu ọpọlọpọ ilewiwo lulẹ na si ikawọ Igbimọ Munisipa Eko lati ṣe e, nitori Igbimọ na nikan ni ise na tọ si.



Oloye Kosoko ti o ṣe Alaga Ipade ti Ẹgbẹ Ilu Eko pe gbogbo enia si ni o duro ti o mba awọn enia ipade na sọrọ yi.

### LAKAYE ORO

Maṣe leri ara rẹ ni ti ọjọ ọla, ni ori iwọ ko mọ ohun ti ọjọ kan yio hu jade.

OWE 27:1

PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY---GET REDIFF-SION

# Bi Oju Ba Ri Oran A Wo o Fin

Lati oju ewe kẹta

ṣugbọn ki nwọn fi eti sile lati gbọ gbogbo alaye ti on o se lori ọran na ni agbọye.

Ninu alaye rẹ, o fi han won pe, nigbati awọn gbọ pe Jimọ fẹ lati fi ọmọ yi lọkọ ni ilu keji ati pe o ti gba ogoji pọnun lọwọ ẹniti o fẹ lati fi ọmọ na fun ni awọn ba lọ mu ọmọ na pẹlu aṣẹ baba rẹ.

Ni ọjọ keji ti awọn mu u ni Jimọ Ojiwonibikaku lọ si ile ọkọ aburo rẹ na lati ja ija; nitoripe adehun ti o ni pẹlu ẹniti o ti gba ogoji pọnun lọwọ rẹ ko bọ si mọ. Gbogbo ẹni a ti o wa nibẹ si bẹ Jimọ na pe ki o ma ṣe ja, ki o mu suru, awọn fi Olọrun bẹ ẹ.

O ni on gbọ, ṣugbọn ki Nasiru Adegboye ọkọ iyawo majafara o, ni o ba fi pada lọ si ile rẹ, nigbati o di pe gbogbo rugbodiyan na tan nilẹ ti o di pe iyawo nlọ si ile baba rẹ lati lọ ki wọn ni Jimọ ba bẹrẹ si yọ ọ l'ẹnu pe ki o ko ẹru rẹ ki o si lọ si ọdọ ẹniti on ti gba owo (£40) lọwọ rẹ.

Esi ti aburo rẹ fun un ni pe "Olọrun ti da on pẹlu ọkọ on pọ ẹyani ni pe on ti loyun. Popoola Oyeniyi aburo ọkọ sọ pe ni iṣoju on gangan ni Jimọ ṣe sọ pe bi Olọrun ba ti da a lohun ki o dide ki o ma a lọ inkan diẹ leyun. Iyawo na si lọ si ile ọkọ rẹ ni ọjọ na.

Ni ọjọ keji ni Jimọ ranṣẹ pe e pe ki o wa mu oogun ara-riro. Iyawo ko mọ pe, oogun oyun-ṣiṣẹ ni, o si mu u. Nigbati o di ọjọ kẹta ti o ti mu oogun na tan ni oyun na ba walẹ pẹlu ipa laipe ọjọ.

Sibẹ-sibẹ ọkan ọmọ ko kọ ọkọ rẹ silẹ. Eyi ni o bi Jimọ Ojuwonibikaku ninu de aye ti o fi le ọmọ na ni magun si ọkọ rẹ, ki ọkọ aburo rẹ yi le ku ki Jimọ Ojuwonibikaku ba le ri aye lọ fi aburo rẹ na fun ẹniti o ti gba ogoji pọnun [£40] lọwọ rẹ.

Olore sọ pe laisi ani-ani Jimọ ni o le aburo rẹ ni magun fun ọkọ rẹ nitoripe bi ọkọ iyawo na, Nasiru Adegboye ti ba iyawo rẹ na sun tan ni o dipe ki o ma a mu omi bi igere ti nwọn fi npa ẹja lodo

Awọn ilu ṣe iwadi ọran na lọwọ Jimọ ṣugbọn o sọ pe on kọ. Nigbana ni Olore Ire sọ pe ki nwọn bẹ ẹ nitoripe "Agbọn sẹ Oyin ṣẹ oju oloko ni o wu gudugbagudugba yi.

E o ma a gbọ bi nwọn ba ti fi ori ọrọn na ti si o.

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi, iwaju ni ọpa ẹbiti nyin yio ma a re si o, ẹ ko ni ko agbako "magun" o. Oju ko fẹraku o.

# Nwon Si Ere Alufa Father Coquard

Lati oju ewe kini

kakiri ilu Nigeria ti o ba ti ṣe iwosan fun fi nrohin rẹ pe Dọkita bi Alufa Father Coquard sọwọn ninu awọn Dọkita, nipa iṣẹ iṣegun mimọlo ati iwa rere, o ta ọpọlọpọ yọ.

Fun odidi ọjọ mẹta gbako ni nwọn fi ṣe ajọyọ na pẹlu oriṣiriṣi ere aṣeyẹ ati fun aṣeyẹ ọdun Jubili fun awọn Ẹni-ọwọ Father J. S. Young ati Father J. A. Kilbey, Ẹniọwọ Julọ Archbishop Taylor ni o ṣe Alaga aṣeyẹ na, Ọgbẹni I. F. W. Schofield Ajẹlẹ Agba Abẹokuta ni o ṣe Gbakeji-Alaga. Awọn ti o sọrọ nibẹ ni Oloye J. O. Kashimawo ati Ọgbẹni S. O. Ajala.

Diẹ ninu awọn ti o wa sibẹ ni Ọlọla Adedamọla, awọn Oloye V. B. Ọdẹbiyi, Laṣọju ati Afunku, awọn Alufa Father Shepherd Rice, Father Bramiff, Ọgbẹni Sanusi ati Adeniyi, Iyaafin I. W. Schofield, "Sister" Benedict ati Dunston awọn Ọgbẹni T. A. Ṣofoluwẹ, J. M. Ọṣimosu, Rẹmi Shyllon, J. A Ṣolankẹ, J. Akirẹmi, P. Sanyaolu, A. Fọlarin, ati Omidan Kẹhinde.




Aworan - Ere Father Coquard ni awọn enia nwo Foke yi


# Atura Ipara ti o Yanilenu



O nmu awọ-ara ṣe

O nmu Irora kuro

O si nle gbogbo Otutu lọ



Sa Ma Fi Pa a



"Mentholatum" jẹ ipara ti o nmu ara enia se bi idan. Bi ara ba ndun ẹ, bi o ba ni ẹfọri tabi irora, tabi otutu-kotutu to ba nyọ ẹ lẹnu, "Mentholatum" ni ẹrọ rẹ. O rọrun pupọ lati lo, yio si ṣiṣẹ bi idan, yara pa ibi ti o ndun ẹ. A jẹ fi idan ni "Mentholatum". On ni o dara ju gbogbo egbogi ipara lọ. Tete lọ ra idẹ tabi agolo rẹ kan loni.

Bere Fun Mentholatum



O wa ninu agolo ati idẹ.

Eyi ti o ṣe pe, awọn The "Mentholatum" Co. Ltd. (Est. 1889) Slough, England lo ṣe gan an.

MENTHOLATUM





RALEIGH

THE ALL-STEEL BICYCLE

Alope titi aiye ni

Ni igbẹkẹle si Raleigh pe ibikibi ti o ba fẹ lọ ni yio gbe ọ de pẹlu irọrun ati igbadun. Inu re a si dun lati ma a fi han bi o ti lagbara ati bi o ti ni ẹwa to. Gbogbo ẹya ni Raleigh le gba bi o fi wu ki ẹru o po lori re to. Agbara RUGG re po, alope gbere titi laelae ni.

Keke Raleigh ti o ba ti ni ami yi "2030" High-Strength, High-Carbon Steel Tubing ni a fi ṣe e.

Only a genuine RALEIGH carries this mark—LOOK FOR IT!

Ibiti nwọn gbe nṣe awọn ogunlogo keke ni a ti ṣe e. Lati ọdọ awọn ti o ti wa ni Raleigh Industries Ltd. Nottingham England.


Printed and Published by the Amalgamated Press of Nigeria Limited, ... Street, Lagos.